# ENMO RE! OBINRIN DI OKUNRIN NI KOTU EGBA

Drink Coca-Cola
STANDARD NEW KING
SIZE 4D SIZE 8D
See that you pay the correct price.

ELETI-OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

6 & 7 BOOKS OF MOSES
LEDE YORUBA
15/-
A LE RI IWE YI RA NI OSHODI COMMERCIAL SERVICE
36 KING GEORGE AVENUE YABA
ATI NI
62 IDIKAN ROAD IBADAN

VOL. X No. 563. ELETI-OFE LAGOS, SATURDAY, MARCH 15, 1958. KOBO MEJI (2d)

## Enmo Re! Obinrin Di Okunrin Ni Kotu Egba

Nse ni gbogbo awon enia ure ti f.le si Kotu nigbati irohin kan wipe, obinrin kan yipada di okunrin ninu kotu li Abeokuta.

Okunrin kan, ti nwon npe ni Oso lo mu omobinrin kan ti nwon npe ni Molajo wa si kotu wipe, omo mefa lo bi fun on, ko si duro lati setoju awon omo nwonyi ki o to ba oko miran salo lati odun kejilelogbon, ki on to wa ri mu ni Eruwa. On ke yonu wipe ki o tun wa fe on, sugbon ki o wa joko lati se itoju awon omo re.

Adajo bere lowo Molajo wipe so! idi oro ni o gbo yen, ewo ni o ri so si oro na?

Molajo dahun wipe, Adajo, ako ma mo okunrin yi ri, emi pelu re ko si pade ri, jeje mi ni mo njo larin oja Iyaga Eruwa nigbati Orisa Sango gun mi. Gbogbo won bu serin ninu kotu, Adajo so wipe, bi on ba wadi pe iro ni Molajo npa, on yio je niya. O pase wipe, ki nwon lo pe awon omo re wa.

Nigbati eyi akobi de, o wipe ha! iya mi niyi. Adajo dahun pe, kini ehun ti o ku ti o fe so nisisiyi? Molajo dahun pe, iwo adajo, nso fi han o nisisiyi ti Sango gun mi pe, iro ni Oso pa mo mi, lo ba tu aso re o di okunrin gidigba, nse ni Adajo tare gba odi keji salo, ni gbogbo Kotu ba tuka.

## Omo'ba Adedoyin Di Alase Ile Igbimo

Ni igba akoko ni apa je ilu Nigeria ni oye Alase Ile Igbimo (Speaker) Ipinle Iwo-orun ti awon fi omo'ba Adeleke Adedoyin je ti awon ti fi Ogbeni D. C. Osadebay j'oye igbakeji re, nigbati awon Olopo mejeji yi omo egbe Ogbe Ile igbimo ni won nan.



Omo'ba Adedoyin ni yio ro'po Ogbeni Richard.

Ade. Doherty, enitii a fi j'oye Onidajo Kotu ile Iwo-orun. Olola Ogbeni A. A. Adelomo, omo egbe Afenifere (A.G.) ni o dagi imoran po ki a fi omo'ba Adedoyin je oye Alase na ti olola Ogbeni Oyalowo omo egbe Alakoko si gbe lese.

Lesekanna ni Olola Alhaji Gbadamosi na da ni imoran po ki afi Ogbeni Osadebay j'oye igbakeji Alase ile Igbimo.

Eyi fihan wipe iwa ifarabalé po ade ni arin ijo ni ni ijoba ati ijo Alatako Egbe Iwo-orun. Eyi wa wa o.

## Omo Ademola Di Adajo Agba Ile Nigeria

Ko ni botiri ni ayo to gbaffinna lokan opolopo enia nigbati a gbo wipe enia dudu ni awon yan si ipo adajo agba fun gbogbo ile Nigeria. Enikeni awon yan na ni Sir Adetokunbo Ademola.

Sir Adetokunbo Ademola yi ni akobi omo kunrin fun Alaiyeluwa Oba Alake Abeokuta, a bi ni ojo kini osu February ti odun 1906. O bere eko iwe re ni Eko ninu ilewe Saint Gregory ati King's College o si sise nile'se ijoba ni Eko ki o to lo silu Oyinbo lati ko ise Loya.

Nigbati o yege ninu ise Loya ti o pada de ilu Eko o sise nile ise Attorney General o si tun se igbakeji Solicitor nile Enugu ninu odun 1936. O di adajo Kotu Kekere ninu odun 1939 l'odun na l'odi igbakeji Adajo (Puisne Judge) ipo yi l'o wa titi di odun 1955 ki a to yan si ipo adajo Agba ti Ipinle Iwo Orun (Western Region) aye ti o je wipe on ni enia dudu ti akoko gbe si iru ipo be nile Nigeria.



Lodun 1957 ni Oba Obinrin ilu Gesi fi oye nla da lola o si di adajo agba fun gbogbo ile Nigeria ninu odun 1958 yi.

Ara Ake majo,
Omo Ere lohun,
Ara Ake majo
Omo Ere ku dawonu
Omo Oloka merindinlogun
Omo Elere mefa ti nwon
wariko ti nwon njohun arawon
l'Ake meji
Ake ko ma lo Ogun
Ake ko ma figi Ogun lana
Ake ko ni jori adilokun
Afi Ori apon lewe'ran
Omo Erin jogun Ola Owo aran o.

## Imoran Fun Omode

Bowo fun agba ki ojo aiye re le pe lori ile.

# Alade Odunewu Nilu Oyinbo



Ogbeni Alade Odunewu ti a mwo nimu aworan yi ni ijoba Federal fun ni aye lati lo se ise fun iwe irohin kan nilu Oyinbo ti nwon npe ni Worthing Herald, gegebi irohin kan ti agbo, on ni a nwo ti o nfi oro isoro ba eniti o ma irohin na wa soro yi.

Odunewu je Olotu iwe irohin Daily Service nilu Eko, on kanna ni igbakeji olotu iwe irohin Nigerian Tribune, on lo si se irohin irin'kakiri'de irin ajo oba nilu Oyinbo nigbati o wa be wa wo ni Nigeria. O si ko ise iwe irohin nilu Oyinbo ki o to pada wa sile.

No. 73/S. 2/633

## Classified Advertisement

The Director of Education, Western Region, wishes the following persons to inform him of their present address:-

| Name | Last Known Address |
|---|---|
| 1. Thomas O. Isabowa | c/o H. M. Prisons, Ilesha, |
| 2. John O. Eze | P. O. Box 273, Ijebu-Ode. |
| 3. J. A. Adenuga | c/o Produce Inspection Office Ilaro |

The Director is anxious to communicate with the above persons in connection with matters pending before the Teachers Council constituted under the Western Region Education Law, 1954, and which will have to proceed in their absence if they cannot be found.

AG: DIRECTOR OF EDUCATION,
WESTERN REGION

# Olopa Oba Ke Gbajo Puro

Okunrin kan ti awon olopa ra mu fun esun apania awon si gbe oro okunrin na duro niwaju kotu giga, Adajo bere pe kini esun okunrin yi ?.

Atako – Okunrin yi je odaran to pa enikeji re ni ojo kewa osu January.

Adajo – Ngbo ! Iwo odaran yi o jebi tabi o ko jebi ?

Odaran – Rara o ! Adajo nko jebi iro ni Alatako yi pa mo mi. Kabiyesi.

Adajo – Kini o ri ki o to so wipe iwo ko jebi iwo ha fe so wipe iwo ko pania ni bi, abi iwo nro ri so ?

Odaran – Te ! Kabiyesi Adajo idire ti mo se wipe nko jebi ni wipe, ni ojo kewa osu January mo wa ninu oko ti mo mbo lati oja Ejinrin si Eko ofufu di wa lowo papo. Sugbon ni ojo Monday osu na ni mo pa enia.

Adajo – That is right kini o tun fe so si?

Odaran – Ohun ti mo nfe ki o se fun mi nisisiyi ni wipe alatako mi puro mo mi mo si fe ki adajo ba mi gba ogoji poun lowo re ki nko fun awon omo mi ki ato ku.

Adajo – There you are, enyin olopa eyiti mo ti nse ikilo re fun nyin ni yi mo fe ki alatako ma ridi oro gbogbo ki o to de iwaju mi sugbon nitoripe koridi oro na daju ki o lo san ogbon poun fun odaran ki a to ma ba oro re lo. Iro ko ye olopa oba nitoripe awon ni emi ilu.

## LIBARTY STADIUM



Oloye Awolowo lo fi ipile ile ere nla kan ti a npe ni Liberty Stadium lele.




## ORIKI BAMWO

Bamwo ðe, alajala omode agbomola bi orisa, akokoluko ogun ti nda mo l'ykan igbona, atata ogun ti npe cata re warawara a je bi idan, a gba bi omi ibon. O s'abiku di ikugbagbe, o s'omo di nhehin l'ore. Iko ri i sa, Ibo ko l'ona tagiri. aiperi ri d'ekun iyonu Olugbala l'omo ti ayagbe orin o kapa inu wo, o la jedi l'abapa, gbogbo abiyamo nyo sese, Ela ri i e reje. Orere ri i o na'gbe bo'ra, Eri npa'lomo lodilese, ere ikoko, kosemani awon abiyamo, eni araiye nifeda ra. O de'lu Ibo, o dega, o de'le Hausa, o d'oba, gbogbo Onisegun l'o so pe ko legbe, gbogbo omode lo lafi e fun ilera.

IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4/- owo oko 1/6d fun Igo kan.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Dengo Bridge, Street, P.O. Box 2, Ebute-Metta.

## Itan Awon Ogboju Ode Loke Amilala Amilolo

Lati Ọwọ Ẹsọ
(Apa Keje)

Lẹhin ti awọn Ogboju Ọdẹ ti fọ Afin ọba tan irohin ti gbode kan wipe awọn ajeji enia ti fọ afin ọba, Okete gbọ o ba Olu-Igbo sọrọ ki o ba wọn koya na.

Nigbati awọn Ogboju ọdẹ ndehinbọ lati Afin wọn gbagbe ikilo ti a fun wọn wipe, ki nwọn ma rin si apa ọtun. kaka ki wọn rin si ọtun nwọn nie rin si osi. Ogbori-ejo sa kigbe pe ẹnyin ọmọ iya mi e ma ṣe jẹki a gbagbe ọrọ ti Ọkẹrẹ sọ fun wa wipe bi a ba npada bọ ọwọ ọtun ni ki a ma rin si.

Okete tun pe Olu-igbo ki o da ọna ru fun wọn, oyi oju wa bere si ko gbo-gbo awọn ọdẹ na, tobẹ ti awọn nla gbongbon Jegi-legbo-ṣogun, ja ewe lọtun o ja losi, o p'ọfọ si, oyi na si duro.

Arọni Kebesi wipe- Isa o lesekanna igbo gbina niwaju o gbiana lehin o si ejo balabula bọ wa. Ogunfumi-nire yọ ado idẹ o na si oju ọrun, ojo si bere si rọ. Arọni afe fo ejo na beni Kanko-kanko ba na Akara-ba si i, o ka ni akatan, o si pa aroni na.

Bi Dalemọ - fegun-lọtọ ti gboju soke ṣe ni ogun awọn ẹranko tun ṣe yọ, o kigbe bayi pe ya-koko, lese kanna awọn ọdẹ ti mura i j a. Awọn ẹranko nwọnyi nsunku bowa ola-balaku awọn ọdẹ na si da ẹrẹta sile nwọn fi yan ọna sile de wọn.

Nigbati awọn ẹranko na de ibiti ẹrẹta wa, ile gbe eran miran mi. eso omiran ṣe oju omiran fọ. Ohun ti awọn ọdẹ nwọnyi t u n na ri si wipe Oke ola kan ti ko ṣe gan ka wọn niwaju ọgai nwọn si ngbọ hiho ariwo omi okun ti o nru jọwa lati ka awọn ọdẹ na nọ ibi oke yi ko ṣe gun.

Giga oke na to adota ṣe si oke ọirun omi okun ti o mbọ papa ga to adota se. Awọn Ogboju-ọdẹ ko

(Wo yoku loju ewe kẹrin)

# Ogun Egba

**Balogun Ogundipe ati awon omo ogun re duro gboin-gboin niwaju ogun Idahomi ati Balogun Abowaba nigbati Idahomi fi dandan le pe a fi bi nwon wo ilu Abeokuta.**

**Nigbati awon obinrin egba gboro yi nwon dide lo soju ogun nwon si nfoko tutu fun awon omo ogun. Nigbehin awon Egba segun.**


## Igbadun wa ninu

## Ọti Heineken's




*Orun didun pẹlu agbara lo sọ*

## Ọti Heineken's

*di Olokiki laiye*

# E L E T I Q F E

A-NJU-WỌN KO SB WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI-QFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. X. NO. 563. LAGOS, SATURDAY MARCH. 15. 1958


## Ọmọ Ademola Di Adajo Agba Ile Nigeria

Didun inu ọpọlọpọ enia ni yio je yika gbogbo Ile Nigeria wipe Adajọ agba ti ipinlẹ Iwọ-Orun, Ọlọla Sir Adetokunbọ Ademọla ti iṣe ọmọkunrin bibi inu Alaiyeluwa Sir Ladapọ Ademọla, Ọba Alake ti ilu Abẹokuta ni Gomina Agba yan si ipo Adajọ Agba fun Olu ilu Nigeria (Federal Capital of Nigeria) nilu Eko. On ni yio rọpo Sir Foster-Sutton Adajọ Agba ti o gba isinmi af'ẹhinti gb'owo kuro lẹnu iṣẹ.

Eyi lo di ẹkeji ti ao gbe Sir Adetokunbọ Ademọla yi si ipo giga arakuyamu bayi ni akokọ on ni awọn yan si ipo Adajọ agba ni ipinlẹ Iwọ-Orun (Western Region) ninu ọdun 1955 On kanna ni Gomina agba ile Nigeria tun yan si ipo nla ti Adajọ agba fun Olu ilu Nigeria nilu Eko. Orire pataki ni eyi jẹ.

Sir Adetokunbọ yi ni enia dudu ti o kọkọ gba agbega si iru ipo nla bayi nilẹ Nigeria afi eyi ba Gomina Agba yọ fun ero rẹ to piye pọ mọ ti ọpọlọpọ enia nilẹ Nigeria ati pataki nilu Eko wa yi a si ba ẹni-ọla, Sir Adetokunbọ Ademọla Adajọ Agba gbogbo ilẹ Nigeria tiun na yọ ki Oluwa ran lọwọ ninu aye iṣẹ rẹ na ni adura tiwa.

## Imoran Fun Enyin Abiyamo


Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmode ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati oriṣiriṣi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

, O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10. VICTORIA STREET, LAGOS.


## FA OGBON ATI IMO YO IDIJE TI YORUBA (EKETA)

### £200 Ni Fun Ebun Idije Yi

IPO EKINI £120; EKEJI £50; ẸKẸTA £20

£30 wa fun awọn miran ti o ba tun ṣe daradara

AKIYESI: Fi lẹta kan si ibi ti o ṣofo ninu awọn orukọ kọkan ti o wa ni isalẹ iwe yi. Lẹhin na ki o fi idahun rẹ sinu apo iwe pẹlu Postal Order 2s 6d (ṣile meji abọ) ki o si fi ranṣẹ (by post) si MANAGER, AFRICS NEWS AGENCY, PRIVATE MAIL BAG No. 5164, GENERAL POST OFFICE, IBADAN. NIGERIA. 1s. (ṣile kan) jẹ owo afikun orukọ ti ẹ ba rope o tun yẹ dipo awọn kan ti akọkọ. Ẹ o fi gbogbo wọn sinu apo iwe kanna. Ẹ le lo iwe miran dipo fọmu yi lati fi ṣe idahun idije yi.

| IDAHUN | ITỌKASI IDAHUN |
|---|---|
| 1 ALA—— | Ọba wo lo jẹ pataki julọ ni ilẹ Yoruba? |
| 2 ——RINDIL—— | Ọba melo lo ni ilẹ Ekiti? |
| 3 A——JỌBI | Eyi jẹ orukọ Yoruba |
| 4 ———SAMI | Eyi jẹ orukọ Yoruba |
| 5 ỌLỌ—— | Eyi jẹ orukọ kan ninu awọn ọba ilẹ Yoruba |
| 6 A—A | Eyi jẹ orukọ ilu kan ni ilẹ Yoruba |
| 7 ———MAWE | Orukọ ọba kan ni ilẹ Yoruba |
| 8 MOLA—— | Orukọ Yoruba. |

Oruko ..........................................

Address (Ibugbe) ..........................................

..........................................

Iye owo ti mo fi ranṣẹ ..........................................

Tete fi idahun rẹ ranṣẹ ki toto ọjọ Monde, 7th April, 1958. Esi idije yi yio jade ninu "IWE IROHIN YORUBA" ni ọjọ Mọnde, 14th April, 1958.

No. 73/S. 2/629

## Director Of Public Prosecution's Office

Applications are invited from suitable qualified candidates in the Government Service who are not below the rank of Senior Clerical Officer and whom their Heads of Departments are prepared to recommend to fill a vacancy of Assistant Chief Clerk in the Director of Public Prosecution's Office Western Region, Ibadan.

Salary-Scale D.4 £390 x 18 - 468 x £24 - 492.

For further particulars and method of application. please see Western Region of Nigeria Gazette No. 12 Vol. 7 Notice No. 184 of 27th February, 1958.

Closing Date 15/3/58.

## Itan Awon Ogboju Ode Loke Amilala Amilolo

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

mọ ohun ti awọn le ṣe mọ ọgbọn pami mọ wọn ninu awọn ko mọ ohun ti awọn tun le ṣe mọ. Nigbana ni Afinka wa ranti egbogi kan ti iya rẹ agba ṣe fun fun Igbala.

Nigbogbo akoko yi o mi okun ko ku ju iwọn ọgọrun ese si ibiti awọn wa o dide o ni ẹyin ọmọ iya mi, Igbala de olukuluku e mu ara nyin dani ki enikan si fi ọwọ keji mu ọn dani o si pe ọfọ bayi pe ,A-gbe-fo, loju kan nsẹ ni gbogbo wọn ba ara wọn lodikeji oke na. Inu awọn ọde dun iye wọn si soji koiti pari, o di ose to mbọ.

## Orin

N'Ijaye ni awọn bi wa si o (2) Baba wa pẹlu won lo tele N'Ijaye ni awọn bi wa si

# Lasebikan Filu Soro Ninu Oyinbo



Ogbeni onilu ti o duro ti a awo yi ni E. L. Lasebikan. O lo ba awon omo wewe ti o wa ninu ilewe kan soro ninu ile kan nibiti a afi awon ohun ataiyebaiye pamo si. Awon omo ti o duro ti won fe gbo bi ilu na ti nsoro niwonyi :-bere lati owo osi: David Revell, Joe Adams, Clifford Martindill, Norma Forder.

Nigbati awon pe Lasebikan pe ki o wa ba awon omo kekeke soro nipa ile Nigeria, nigbana ni o fi ye won wipe, bi Yoruba ba nlu ilu aposran oro ni awon fi nso.

Awon omo na here wipe inu awon yio dun bi alagba na ba le ni ilu na fun won ki nwon gbo. Ilu na lo nlu fun won yi.

Ninu awon ilu na ni Aponran Batakoto, ati Bembe wa.

## Awe Dee! Oko Imale

Olorun oba so fun Anobi Muhamad wipe ki o wi fun gbogbo awon ti o ba gba Olorun oba gbo, a ti pese akoko awe gbigba sile fun nyin fun ojo die gegebi a ti se fun awon eni isiwaju ti nwon gba Olorun gbo, ki o ba le dabobo nyin kuro ninu awon ohun ibi gbogbo.

Eniti o ba mbe lori aisan, tabi oluware mbe lori irin ajo ko ni gbawe sugbon oluware yio gba awe dipo iye ojo ti oluware ko fi gbawe na.

Sugbon eniti o ba ri wipe, awe gbigba je ohun isoro fun on, ki eni na bere si bo tabi ki o ma fun awon alaini ni onje. Enikeni ti o ba gbawe na gegebi a ti se ilana re yi, yio se orire nitoripe ohun rere ni Awe je fun nyin, bi o ba je wipe enyin mo. Quran 2. 183-184.

Ni asiko osu Awe ni ebi ma npa awon elesin Kiriyo, nitoripe Ogunlogo awon ti o nta onje ti awon enia nje, je kiki Imale, eyi ni ko ni jeki nwon ri onje nwon ra onje ra ni akoko owuro.

Nigbati awon omo Israeli wa nile Egypt, Olorun pase pe ki nwon gba awe ninu osu Ramulana, ki awon si se Duhaya tabi eyiti awon npe ni ase odun Ileya, ti awon Kiriyo npe ni ase Irekoja.

Bi o ti pa lase fun Muhamad ati awon omo Isreali, Anobi Ibrahim ni Olorun koko pa iru ase yi kanna fun. Eyi nidi re ti awon se npe Imale ati Kiriyo ni omo Ibrahim.

Sugbon nisisiyi, o dabi enipe awon Kiriyo kobi kita fun ase ti a ti pa fun Ibrahim mo. Ako gbo nibikan wipe ki awon Iran kan gbawe to tayo ogbon ojo ri.

Awon ti a gbo pe nwon gba ogoji awe tosan-toru ko nse pelu oju lasan beni ko si nse ife inu won lati se be bikose pelu tulasi.

Enia merin ti a gbo wipe, nwon gba ogoji awe tosan-toru ni Enoku, Mose, Elijah ati Jesu, awon meterin nwonyi, ko si eniti o mo busun won Awe oko Imale, awe ni oko eniti o ngba, o jare.

## Awon Omo Ibile Erinmo Se Ipade

Lati owo S. O. OBISAKIN
IBADAN

IBADAN. Ipade gbogbo gbo kan ti awon omo Erinmo se ni ojo 23rd osu February, ni ojo abameta ninu ile Isin St. Peters Erinmo.

Okan ninu asoju ilu yi ninu ipade agbegbe ti Aiyepeju Council Mr. P. A. Falodun ni o pe Ipade Apapo yi.

Imoran fun itesiwaju ilu yi ati Iwadi ohun ti ko ye ni lo je pataki ohun ti a se ninu ipade agbajopo na.

Awon Oloye ilu yi ati awon enia saraki-saraki ti o je omo ilu yi ni o wa si Ipade na. Die ninu awon ti o wa si ipade na ni Mr. D. O. Oladeru, Alaga ipade nla yi. Noah Oluwadaisi, akowe ilu S. O. Obisakin onisowo lati Ibadan, Mr. A. Sobiejo lati Ikeja Issac Anjorin E. Folami ati Joshua Babajide gbogbo won lati akufo; J. A. Ol lati Lalupon Erinola lati Shaki ati opolopo ho Oshogbo ati ni ibi gbogbo ni agbegbe Iwo-orun.

A o gbiyanju lati te awon oro pataki ti a so ninu ipade yi si iwe ni ojo iwaju.

# Abede Alakoso Eleti—Ofe Lati Ilu Oyinbo



Awon gbajumo enia ti a nwo ninu aworan inu iwe wa yi, lati owo osi, ni Ogbeni Alex Ola. Oni, ti o da'wo te'badi Ogbeni E. Effiong Olotu Iwe Irohin kan ni Calabar Ogbeni Taju Thompson Alakoso Iwe Irohin Eleti-Ofe (Managing Director) Ogbeni Layiwola Mabinuori, okan ninu Olotu Iwe Irohin Daily Service ati Ogbeni A. S. Badru Transport Manager, G. B. Ollivant Porharcourt nigbati nwon lo pade Alakoso Iwe Irohin wa ni idi oko Ofurufu ni Ikeja ti o ti de Oyinbo pada de ni igba keta ti o ti nlo be awon ilu Oyinbo wo.

## Ona Ara Ni Ise Olorun

EKO. Nibi iṣẹ kan ni Eko, ọkan ninu awọn oṣiṣẹ ibẹ jẹ ẹniti o fẹran orun sisun lẹnu iṣẹ, nipa bẹ nwọn gbe lati Ibadan wa si Ebute-Metta nigbati ko ye orun sun, ni nwọn ba gbe lọ si Eko.

Ni ọjọ kan ti ọga agba de (Store Manager) ti o tun ba loju orun. O ji i o si ranṣẹ pe ọga kekere o bẹrẹ si sọ bayi wipe, Kini ki nten ṣe nipa rẹ Iwọ Joe orun ni o sun si Ibadan ti awọn si fi ẹjọ rẹ sun mi ti mo ni ki nwọn gbe ọ lọ Ebute-Mẹtta bakanna orun lo tun nsun nibẹ ki nto wipe ki nwọn gbe ọ wa si Eko. Nigbati o si de ilu Eko sibiti iran ko nṣu oju sibẹ-sibẹ o tun nsun.

Nkọ da ọ duro ṣugbọn ngo fi ọ polowo ọja mi. O fun ni Pyjamas kan (ẹwu awọsun) o ni ki o lọ joko si isọ ẹwu (Pyjamas). O wa polowo ọja bayi pe (bi ẹniti ko ri orun ba wọ ẹwu yi yio sun daradara o fi kọ si ara isọ ewu Pyjamas).

Ọmọkunrin kan ti ko ri orun sun nigbati o de isọ Pyjamas ti o ka ti o si tun ri ẹniti o wọ iru ẹwu na ti o ti sun fọnfọn ọra okan. Bi o ti dele ti o gbe ewu na wọ nṣe ni orun bere si kan o si sun fọnfọn.

Laifa ọrọ gun gurosa merin ni gbogbo iru ewu yi ti awọn ni lọwọ gbogbo ra ni nwọn ra tan kedere nṣe ni nwọn tun ṣeṣe mase fun omiran awọn si fi owo kun owo Joe Ọlọrun. E o ri i, ọna ara ni olorun ngba se ise re nile aiye.

Ṣugbọn bi enia ba fi ori we "Modaku sere" oluwere le daku ko ma si ji mọ o.


## Kere o!

Ati ni orisirisi ogun German to ṣeṣe de, fun oiyeru aisan ọkunrin obinrin. Tete wa ra tiẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.

# Olojo Ibi Ojo Ayo

EKO. Jantere ni awon ero nwo ni Alibu Street ni apa adugbo Itolo nigbati Ogbeni Sule Majeraahun gniti opo awon enia wo, ti awon ope ni Ofe nse ariya ojo ibi re, awon omijo njo awon Omu joko ti apo-ti Bia beni awon alase nso, ero si nso.

Ese gbogbo awon alafa Lemonu ati awon Alhaji le pe sibi olojo ibi ti o di omo odun mokandilogoji yi, nwon kewu, awon ke wusuba, nwon si se adura emi gigun fun Sule Majenrahun.

Die ninu awon gbajumo ti o wa sibi ayo ojo ibi nani Ogbeni Lemoriyu A. Ojo, S.A. Abudu Isaac Thompson Saola Balogun, Wahabi Adegina, Ferman Johnson ati awon omidan ati Iyafin Idileko Siam Abeke Bisiu nse ni awon afi oso taka dara won.

Emi a se opo re o.

### JAPAN KO NI GBAGBE NIGERIA

TOKYO. Ogbeni kan ti awon npe ni Tanaka Yasaka ti o nse okan ninu awon igbimo Japan le soro yi pelu edun okan fun awon igbimo wipe apapo gbogbo awon omi oola ti o ba ogun igbehin yi lo to egorun oke mela.

Awon omo ogun Japan ti o ba ogun lo je 1,700,000, awon ara ilu ti ko ogun yare, ti ogun pa je 168,000. Dukia ile wa ti ogun gbe lo je ogidinlogo ora. Lehin eyi awon obinrin ti ogun se di alailoko ala-Ilemo je 2,73,000 ni ko ti se ru o wo.



STOP YOUR BACKACHE
by quick attention to your
KIDNEYS & BLADDER
TAKE
DeWitt's
Kidney & Bladder Pills
and get rid of the poisons in your body that are the cause of RHEUMATISM
JOINT PAINS, BACKACHE and BLADDER TROUBLES
DeWitt's
Kidney & Bladder Pills
In a few hours you will SEE results
(Urine changes colour)

# Arewa Meji Pade Ara Won Nilu Oyinbo



Awon arewa obinrin meji ti a nwo yi ni nse wa obinrin lati ile awon Aganyin ati ti ilu Oyinbo gugbon nilu Oyinbo ni awon mejeji gbe pade yi. Oreko ti ile Ghana ni Monika Amekofia ti ilu Oyinbo ni Iris Waller.

Nibia ni a gbe ri awon arewa mejeji nibiti nwon gbe nso ara won kakiri ti nwon si nfi nkan han ara won.

Gegebi ebun ti Monika yio gba fun ewa re, yio lo be awon ilu nlanla wo nile Gesi, ati awon ibi i o lokiki ti a ti ngbo iro won, yio si de awon ibi ise nlanla nibiti a nlo awon ohun ogbon ile Ghana.

Yio de ile ibiti awon ti nso Koko di ooie, ile ibiti a ti nse Keke Ologere Rali ati ise moto.

# A Nfe Asoju

A nfe Asoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ofe lati kun awon Asoju wa ni awon ilu ti a daruko ni isale wonyi-

Abeokuta, Ijebu-Ode, Ijebu-Igbo, Ile-Ife, Osogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ofe Kosoko St, Lagos.

# Ojo Isinmi Odun Imale

**EKO. Gomina Agba Olola Sir James Robertson ti pese wipe ninu odun ti a wa yi, ojo isinmi odun Imale yio je ojo meji fun odun kekere Idul-Fitri April 21 ati 22, odun nla Idul-Kabir ojo meji June, 28, ati 30, nitoripe ojo ose (Sunday) ni 29 osu June, 1958. Ojo ibi Anobi Muhammed, Maoludun Nobiyi Ojo Kan, Sept. 26, 1958.**

## Oba Alake Ba Omo Re Yo



Nigbati Foster Sutton ti o nse adajo agba fun gbogbo ile Nigeria fi ipo re sile ti o si lo gba aye isinmi kuro lenu ise, eniti ijoba ro wipe o to si ipo na ni Sir. Adetokunbo Ademola.

Eniti a nwo ninu aworan yi ni Kabiyesi Sir Ladapo Ademola Alake Abeokuta on lo yo ti inu re si dun gidigidi si ipo giga ti nwon gbe omo re na si.

Nigbati adajo na ri baba re o dide fu u, o si gbowo lowo baba re pelu iteriba. Nigbati Alake re lo ki omo re o de ade Golu o si fi ileke iyun sorun. Agbo pe "Kabiyesi" lo fi ki baba re.

## HOSPITAL PROGRAMME



With the opening on the 5th September of the Ilaro Hospital by the Minister of Health, the Government fulfilled one of the major programmes it set itself out to achieve in 1952. In that year Government announced that it proposed to ensure as soon as practicable that at least one Hospital—either Government or Mission—was established in every Division. This required the building of seven new Government Hospitals, each costing over £75,000, at Auchi, Epe, Okitipupa, Kwale, Ikeja, Iddo Ekiti and Ilaro.

The building of new Hospitals and additions and improvements to old ones has meant that there are already over 1,800 hospital beds, almost double the number in 1952.

*Issued by the Western Nigeria Information Services*

## ADEHUN NI ADEHUN NJE

(O bere lese tokoja)

bosi ito beni awon akoda awonyi yara da sekere sile won si dimo lori won di koko pada sori re. Itiju nlanla si mu ki o sa kuro nilu o si lo pokuuso.

Lati igbana wa ni iru ensfasi bayi larin awon ewis ko ti si mo. Adehun ni adehun nje Enikeni ti o ba se adehun ki o mase jeki o ye o. Awon elomiran wa ti won yio ba enia se adehun ti won yio si mu fi oruko Olorun bura eke pe awon yio se nkan yen ki won ma foiya, sugbon asehinwa-asehinbo omulemofo ni gbogbo rayio jasi ti nwon ko ni mu adehun se gbogbo aiye ti deke, ko si aladehun mo adehun Alagbada lo ku laiye o.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 617 Lagos Phone 23370